# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 932 LAGOS SATURDAY AUGUST 1—AUGUST 7 1964 KỌBỌ MEJI (2D)


## Ijangbon Be Sile Ni Iga Idunganran

# Lehin Iku Adele Tani Yio Joye?

EKO — Orişirişi irohin ni a ti ngbọ lati Isalẹ-Eko lati ọjọ keji ti Ologbe Ọba Adeniji Adele Keji ti waja nipa awọn ti awọn ọmọ Ọba nfoju si lara lati yan sipo Ọba Eko tuntun ni Iga Idunganran. A gbọ wipe awọn Oloye afọbajẹ ti ri iwe gba jaburata lati ọwọ ọpọlọpọ awọn enia ti nwọn nfẹ oye du oye na, eyi ti o fẹ da ijangbọn silẹ larin awọn afọbajẹ ti nwọn npe si Iga Idunganran lojojumọ.

Awọn Oloye mẹfa ni nwọn wa ninu awọn Oloye Eko ti nwọn ni lati f'oba jẹ, awọn na ni Oloye Eletu-Odibo, I.O. Bajulayie, Oloye Akanbi Yesufu Olumẹgbọn, Oloye Ọbanikoro, David Ogunlana, Oloye Ashọgbọn (nwọn ko ti jẹ Ashọgbọn miran) aye iyẹn wa nilẹ, Oloye Oniru tabi agbo Oye miran bi Oloye Ọjọn Agoro.

Ninu ile meje ti nwọn njẹ Ọba si Iga Idunganran bi awọn idile Dosunmu, Akitoye, Oyekan, Ẹshinlokun, Tadeyọ, Olusi ati Adele awọn idile mẹta ni nwọn si nfọwọ sọya nisisiyi wipe dandan awọn ni Oye jijẹ na kan. Awọn mẹtẹta na ni idile Oyekan Akintoye ati Akinṣemọyin.

(wo iyoku loju ewe kẹjọ)

# Iyawo Awolowo Lo Wo Oko Re Ni Kalaba

CALABAR — Ninu awọn alejo pataki ti o wọ ilu Kalaba ni ijẹrin Ọjọ 'Ru ni Iya-afin H. I. Awolọwọ, iyawo Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre (AG) ti nwọn mu lati ọgba ẹwọn lati Eko wa si ibi yi ni ibẹrẹ oṣu ti o kọja yi, ti o wa wo ọkọ rẹ na. On pẹlu awọn ara ile wọn mẹta ni nwọn wa.

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ lati ọdọ onirohin wa ni Ipiniẹ Ila Orun, ọkọ ofurufu ni iyawo Oloye Awolọwọ na wọ pẹlu akọwe ọkọ rẹ na ti o njẹ Dairo ati iyakọ rẹ, Iya afin Awofẹsọ. Nwọn mu kuku (alase) ti o ma nse onjẹ fun wọn ti o ni on fẹ foju kan ọga on lọwọ.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ


## PILGRIMAGE

TO MECCA / MEDINA AND QUDUS (JERUSALEM) E.t.c. E.t.c.

### Arrange Your Travelling

By Air To Anywhere In The World Throught A Reliable And Honest Agents Of

### Messrs T.S. Calfos & Sons

(KAFFO'S CHAMBERS)

10, PATEY STREET LAGOS Phone - 20979
BRANCH OFFICE :- 30, GRIFFITH STREET, E.B. Phone - 44403.



## LAGOS RACE CLUB

SUNDAYS 2nd, 9th, 16th, 23rd AND 30th AUGUST, 1964.

Racing Starts at 3.30 p.m. each day of the Meeting.

**DECLARATION.**

Declaration will be made at the Secretary's Office between the hours of 1.30 p.m. and 2 p.m. on racing days.

Admission Ticket/Programme 4/- per day including Entertainment Tax.

**CHILDREN.**

No Children under the age of 14 years will be permitted to enter the Members Enclosure.

**SWEEPSTAKE.**

On each day's race Meeting a Sweepstake will be drawn on the number of Admission Ticket 1st will be paid £2. 10/-, 2nd £1. 10/- and 3rd 13/
Special Horses from the North entered for the meeting.
Look forward to BIGGER DIVIDENDS.

# Gbigba Owo Ile Fe Bere N'ilu Ibadan

IBADAN—Awọn Kansulu igbọrọ ịlu Ibadan ti paṣẹ fun Igbịmọ ti nṣe eto owo nina ịlu wọn lati da eto gbigba owo lori agbo ile kọkan ni agbegbe tabi awọn adugbo ti awọn wa ni ika vọ awọn alaṣẹ na. Fi fọwọ si eto titun yi ṣe nkan kan ti awọn ṣe ninu ipade Igbimọ Kansulu na ti nwọn ṣe n! Mapo ni Ibadan ni ọjọ Iṣẹgun to koja yi.

Ninu ipade igbimọ na, ẹniti o jẹ akọwe Kansulu na ka iwe kan ti nwọn ri gba lati ile iṣẹ Olotu nipa eto Ijọba ibịle ninu eyiti awọn fi fọwọ si eto titun yi wa pẹlu fi faramọ. Lọwọlọwọ Kansulu na ti fi aṣẹ le awọn igbimọ ti nbojuto eto owo lati ṣiṣẹ lori awọn ịlana ofin titun yi.

Nịgbatị eto ati ofin titun yi ba gberu tan, gbigba owo-ori ati owo-ile yio fara ba awọn ile nla-nla yatọ si awọn ile alamọ ṣugbọn ẹka ẹgbẹ Alakukọ to wa ni Ibadan ko faramọ eto titun na, awọn nị iru ofin titun yi jẹ ohun ini a ati parilara ti o si tun ewu pẹlu. Ninu ọrọ kati Alaga ẹgbẹ na sọ, Ọgbẹni Adeoye Adisa, o ṣe alaye mẹta ti o mu ki nwọn gbe eto titun yi jade.

Ekini ni pe Kansulu ẹgbẹ Dẹmọ ko ni aṣẹ kan lati ẹnu awọn ara Ibadan lati ṣe iru eto bayi kalẹ, nitori pupọ ninu awọn ọmọ ẹgbẹ na ni nwọn jẹ awọn ti wọn ti rekọja lati inu ẹgbẹ Ọlọpa si UPP i fi de ri NNDP ẹgbẹ ti awọn ara ilu ko ti dipo fun ara, t bi tani mọ ri ju ẹgbẹ AG ti nwọn ba wọ ile igbimọ lọ?

Ekeji ni pe nipa ṣiṣe ofin titun yi yio mu ki owo ori ti awọn ara Ibadan ma san lọpọ di lọpọ meji.

Ẹkẹta o so pe nwọn ṣe ofin titun yi jade n! pataki lati jẹ awọn obinrin niya ati lati sọ wọn di ẹru labẹ sisan owo alarede yị.

## Ịre Egungun Ni Ilu Eko

Irohin kan ta si wa leti ni ịle-ịṣẹ wa nipa ọdọmọde kan ti o nleri lati fi egungun rẹ ṣere fun awa Eko ni Dec 3rd ọjọ kẹta oṣu kejila ọdun yị.

Gẹgẹbi irohin na ti tun lọ a gbọ pe ọdọmọde kan ọmọ ọdun mẹrịnla ti nwọn bi ni ilu Omupo ni agbegbe ilu Ibadan ti o ngbe Eko, ti o tun jẹ ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ elegungun yio fị egungun r da-ra ti oju ko ti riri ni ọjọ na.

Orukọ ọdọmọde na njẹ Aworawọ nị ilu Omupo: Awọn ọmọ ẹgbẹ elegungun na sọ pe orịṣịriṣi egungun ni nwọn ti nṣọdun nị ịlu Eko t si jẹ pe awọn janduku enia ma nda ijangbọn silẹ kakiri, ṣugbọn eyiti awọn fẹ ṣe yi ko ni ribẹ nitoripe iru awọn janduku bayi n awọn yio kilọ fun ṣiwaju ki ere na ba le larinrin.

# Arun Sobiya Kolu Ara Ilu Benue

BENUE—Lẹnu lọọlọ yi ni oniwe irohin wa kan sọ fun wa pe aịbalẹ ọkan ti lẹ silẹ ni ilu kan tị nwọn npe nị Lamịnga ati Marmara ni agbegbe Nassarawa ninu ịlu Bẹnue nịbịtị irinwo-dịn-marun enị (395) gbe njaporo arun sobịa, lori eyịtị ijọba ibịlẹ ịlu Nassarawa tun ṣe ịkede nipa rẹ.

Ni nkan bi ọdun kan sẹhin nwọn ti sọ asọtẹlẹ fun awọn ti sobia koln yi, ti nwọn si jẹ ekida agbẹ paraku, nipa bibe silẹ arun yi, nwọn si fun wọn ni imọran lori rẹ pẹlu awọn ileto mi-ad pẹlu.

Ṣugbọn irohin da ni anu ṣeni pupọ lati ri wipe awọn enia inu awọn ileto wọnyi ko suja imọran ti dokita onișegun fun wọn Nisisiyi awọn ilu Nassarawa ti kọ iwe ẹbẹ kan si Olẹtu eto ilera ti ilẹ Ariwa ni ilu Nagiria lati ṣe iranlọwọ fun wọn lati pa itansiwaju arun na.

# Aseyi S'amodun O!

A fi ikede yị la Alakoso iwe irohin Eleti-Ọfẹ Ọgbẹni Taju Thompson ti o nṣe ipalẹmọ ajọdun ọjọbi rẹ ti o bọ si Ọjọ Aje (Monday) ọjọ keta oṣu kẹjọ ọdun yi, yọ. Ni ọjọ na ni Ọgbẹni Taju Thompson yio di ẹni ọgọta ọdun.

Gbogbo ẹnyin ọkawe wa bi ẹ ti mọ Ọgbẹni wa yi si, o jẹ ọkan ninu awọn oṣelu Nigeria, lati nkan bi ọdun ketadinlogun ni o si ti bẹrẹsi gbe iwe irohin ELETI-ỌFẸ yi jade fun ilọsiwaju ilu wa Nigeria yi. Orịṣiriṣi ile iṣẹ nla-nla bi awọn ile iṣẹ ina ẹlẹtrik (ECN) ati Brasserie Nigeria Ltd ni Apapa ati awọn ẹlẹja (Nigeria Fishing Industry) ni o jọga nibẹ pẹlu awọn ile iṣẹ oni panu ayọ Nigeria Alminum Industries.

Pẹlu ọrẹ ati ẹbi ni a ki alakoso wa na wipe o oku ọdun ire, Aṣeyi ṣamọdun.

— OLOTU

E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin ELETI—OFE ti o kun fun irohin aladun lososo.

# Omo Adajo Fadipe Pade Agbako Awon Janduku Nilu Oyinbo

LONDON —Ọmọ adajọ - agba, Ọgbẹni Louis Olubọdun Fadipẹ ti kotu ẹjọ ko-tẹ mi-lọrun ni Ibadan ti o njẹ Charles, ti o nkọ iṣẹ dokita ni ilu ti a npe ni Dublin ni ilu Oyinbo ni a gbọ wipe o pade agbako awọn janduku Oyinbo ti nwọn ko nfe foju kan awọn a awọdudu, awọn janduku na fọbẹ gun un loju nibiti o gbe arin lọ jẹjẹ rẹ ni arin ita gbanbga.

Irohin na ba baba rẹ, adajọ Fadipẹ ninu jẹ pupọ ti o fi wọkọ ofurufu lojiji lọ wo ọmọ na ninu ile awọn alanodi oju ti nwọn gbee lọ ni ilu Dublin na lati ṣe Ọ ọjọjọ oju ti ọbẹ ba ọmọ akẹkọ yi.

Awọn dokita oniṣegun ti o nṣe itọju oju ọmọ adajọ na ni boya ni o le fi oju na riran mọ nitoripe ọbẹ ti nwọn gun un loju na jẹ pupọ jọ.

Lẹhinti Adajọ Fadipẹ ti foju kan ọmọ na tan ti o gbọ bi gbogbo nkan ṣe ṣelẹ, ti awọn janduku Oyinbo ọmọ ita na lu ọmọ rẹ ni alubolẹ, wara were ni o ti ikọ iwe-ẹdun ọkan lati tọka si iwa buruku awọn ara ilu na pẹlu Ọ ọpa wọn ti nwọn ko fẹ foju kan awọn enia alawọdudu, ti o si gbe lọ fun aṣoju Ijọba ilẹ Nigeria ti o wa ni ilu Oyinbo wipe ki Ijọba awọn Irisi (Irish) mọ eyiti nwọn yio ṣe.

A gbọ wipe awọn Ijọba si wa lẹnu ọrọ na, ọmọ alara paapa ko ti kuro ni ile awọn ala'san ti nwọn ntọju rẹ. A gbọ wipe nwọn ti ri ẹnikan mu ninu awọn janduku na awọn ọlọpa si ti wọ Oyinbo na lọ si Kotu.

## Akeko Kan Fidi Daran N'Ilu Oyinbo

LONDON — Laipe yi ni a gbọ pe kotu kan ni London paṣẹ pe ki ọmọ akẹkọ kan Gilbert Ero ọmọ ilẹ Nigeria ti o nkẹkọ ni ilu Oyinbo lọ san poun marundinlogọsan (£175) fun oluko obinrin kan Vera Mabe Smith ti o nkọ wọn lẹkọ ni ile iwe kan ni London ti Ero fi igba kan ṣe ileri fun wipe on yio gbe e ni arede.

Adajọ ni on ko le ba obinrin na wi pe "...kan jatijati ti ko boju mu ni on to ṣẹlẹ si nitori pe o ti gbẹkẹle adehun [illegible] ọro yi ti o fi jẹki wọn ba on lo pọ loju ọna lai ti gbe ... iyawo ṣile, Gẹgẹbi alaye ti adajọ tun ṣe, o ni Iyaafin Smith ko tete kọ ... si ere ... ti Ero nba a ṣe tẹlẹ ri, titi ... igba ti o wi sofun gba gba pe on fẹ fẹẹ, ṣugbọn nipa ... omugọ ti Iyaafin Smith hu, o fi aye silẹ fun Ero lati ba lo pọ.

Adajọ kotu giga na tun ni iru ṣiṣe bayi iba ti mu ki Ero kuku fẹ obinrin na ni iyawo, ṣugbọn iya rẹ lodi si ... nitoripe o ran wa si ilu Oyinbo lati wa kẹkọ nipa iṣe ẹrọ elẹntiriki ni on ko wipe ki o wa gbe Oyinbo ... rara.

Ọrọ ti adajọ tun sọ ni wipe bi ... Iyaafin Smith ṣi wa gẹgẹbi oluko, si ... ni ... lati jẹ ... lati tun kawe siwaju fun oye ... o ti ni ọ pẹlu Ero.

Ki adajọ to pari ọrọ rẹ o ni "bi Iyaafin Smith ti ṣe ... bon to pelu ... aye" fun ọpọlọpọ ọdun ... o tun wa gbe ... ipo ... bayi, ṣugbọn ... ti ... ri ... ẹjọ na ki ... ṣe eyiti o ... owo ọya wa gọbọyi ni sisan.

## Okunrin Kan Fi Iro Pipa Wase

IBADAN—Laipẹ yi ni a gbọ pe ọkunrin kan ti ko ni iṣẹ lọwọ ṣe apamọpamọ iwe ẹri adamọde kan funrara rẹ, ki o ba le dabiẹnipe Oloye Fani-Kayọde igbakeji Olotu Ipinlẹ Iwọ Orun ni o kọ iwe na fun on, eyiti o mu lọ si ile iṣẹ awọn aṣoju ilu Amẹrika ti o wa ni ilu Ibadan lati fi waṣẹ labẹ wọn ki o fi mu ibere awọn alaṣẹ ile iṣẹ na ṣẹ.

Nigbati ọknurin na ti mu iwe ẹri adamọde yi de ibẹ tan, ọkan ninu awọn olotu ile iṣẹ na ba kesi Oloye Fani Kayọde lati wadi nipa iwe na, ṣugbọn o ni on ko mọ nkankan nipa rẹ.

Ọrọ yi ni ọlọpa olotun mẹ a kan, Ọgbẹni Samuel Bẹwaji sọ fun kotu kekere kan ni ilu Ibadan nigbati wa, ti o si fi fuu Ọgbẹni Green ti o jẹ Aṣoju ilu Amẹrika ni ilu Ibadan ni ọjọ kejidinlogbọn oṣu kẹta ọdun yi

Ọgbẹ i Josẹfu, ọdaran na sọ ninu ọrọ idabobo ara rẹ pe "O di ọdun mẹta gbako ti mo ti nwa iṣẹ ṣe ni ilu Ibadan, ṣugbọn gbogbo rẹ lori asan ni."

Ki adajọ to bẹgi le ọdaran na lori ọlọpa, Ọgbẹni Bẹwaji bẹ adajọ pe ki o bẹgi fun ni ẹkun rẹrẹ nitori ẹni ọlọla ti o fi ẹnu kan.

## Ara Mi Le Bi Okuta



Oloye Samuel Ladoke Akintola

(Ẹ ka ọrọ rẹ loju ewe kẹrin)

# ELETI - OFE

(A NJU WỌN KO ŞE WI LẸJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMM
23, Kosoko Street, Lagos, "ELETI-ỌFE" LAGOS
P. O. Box 467 Phone 2337

VOL XIV. NO 932 SATURDAY Aug 1 — Aug 7 1964


## Oro Olotu:

# Tani A-Se-Ma-Lu?

A şe akiyesi wipe lati bi ọjọ mẹta sẹhin ni esi ọrọ kan ti ọre wa, Ọgbẹni M.C.K Ajuluchukwu, ọkan ninu awọn ti o nşe ala oso eto ikede Ijọba Ipinlẹ Ila Orun ni Enugu, sọ lai fi la aye si i bẹrẹsi bige b'Adubi nipa awọn Hausa ati Ibo. Ko si nkan ti o mu wa lọkan lati fi dasi ọrọ na ju ọna ti Gomina wa Ọlọla Nnamid Azikiwe gba lati bẹ lu ọrọ na larin awọn oniwe irohin wẹjẹ, "OUTLOOK" ati Ọgbẹni Eje Agbo, adele Olotu "NIGERIAN CITIZEN" ti nwọn nsọko ọrọ sara wọn.

A gbọ wipe Ọgbẹni Ajuluchukwu ni LABAYIWA ti o sọkọ fi iru fọnna pelu ẹnu rẹ ti o gbọrọ orişirişi A ko si le ba a wi nitoripe loni kọ ni o ti nsọ iru ọrọ bẹ ẹ si awọn agbalagba lara. O nsọ ọ nigbati o wa ni Olotu iwe irohin kan ni Yaba l'Eko ati nigbati o wa ni Pọta (Port Harcout), ki a ma şẹşẹ tun fẹnu kan igbati nwọn şẹşẹ tun gbe soyi aga alakoso iwe irohin Ijọba OUTLOOK ni Enugu.

Ọgbẹni Ajuluchukwu ni oni ẹnu rẹ, nkan ti o ba wu u o le fi i sọ şugbọn bi ko fi i tu agbo ..ọ.

Larinka ni ẹniti o pa on ko şẹ on to bi ẹniti o gbe on şanlẹ loju ogun. Awa oniwe irohin Eleti-Ọfẹ ko faramọ ọna ti Gomina wa, Ọlọla Azikiwe fi gba da si ọrọ na. O dabi ẹni wipe o fẹ sọ awọn iran IBO di A-ŞẸ-MA-LU ẹran Ọba ti o ba şeda şebi, ti n wọ nko o gbọdọ fọwọ kan.

Bi Gomina Azikiwe ba mọ wipe baba ni on jẹ fun gbogbo awọn ara ilẹ Nigeria, şe nkan ti o ba oju mu lati ma gbọ ohun rẹ nigbakugba ti enia kan ti sọ ọrọ si awọn Ibo. Bi o ba ri wipe ọrọ ti nwọn sọ si aşiwaju Yoruba tabi Hausa lara ko dara o yẹ ki o şe ikilọ fun wọn bakanna.

Ẹnyin ara wa, awọn Ibo nikan ko ni ọmọ ilẹ Nigeria ti o gbe Gomina Azikiwe depo ti o gbe wa loni, Hausa ati Yoruba lọwọ nibẹ.

# Churchill: Baba Leje!

A gbọ irohin kan lati ilu Oyinbo wipe ninu oşu yi ni Ọlọla Winston Spencer Churchill ti o fi



# Ara Mi Le Bi Okuta

( O bẹrẹ loju ewe keta )

Ninu ọrọ kan ti Oloye S.L. Akintọla, Olotu Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun ba awọn oniwe irohin sọ ninu ile rẹ ni adugbo Iyaganku ni Ibadan ni Ọjọ Aje (Monday) o ni "Ara mi le kogikogi Dajudaju apata ilu Jibiralta ko ligbara to mi".



## Oloye Samuel Ladoke Akintola

Ọrọ yi ni Oloye Akintọla sọ ẹniti o tun jẹ Aşiwaju Ẹgbẹ Dẹmọ, nigbati o nşe asọle ọrọ lori ọrọ nwọn ni kan ti o tuka saarin igboro ilu Eko pe nwọn ti paa ni kete ti o ti ilu rẹ (Ogbomoşọ) de si Ibadan ni Ọjọ Aje.

Oloye Akintọla tun sọpe ẹnikan ko pa on rara lati pe irohin agbọsọ irọ na jẹ eyiti o ti ọwọ awọn akorira ẹgbẹ Dẹmọ wa.

Şiwaju ninu ọrọ rẹ, o dahun pe ninu gbogbo irin-ajo on titi de opin ọsẹ to kọja, ko si ẹnikẹni ti o daba lati şe on wo, tabi ki on tilẹ ri idiwọ kan. Ẹniti o ba ro ibi ni ibi pada ba.

## ỌRỌ OLOTU

ọpọlọpọ igba şe Olotu Ijọba Gẹsi fẹ fi ile igbimọ awọn asofin sile, o fẹ sinmi dọjọ iku. Ki a ma purọ ọrọ Ọlọla Churchill tobẹ.

Ninu gbogbo awọn oselu agbaiye ko si ẹniti o le wipe bawo ni ti Ọlọla Churchill jẹ ninu ki a fi suru şe ẹto Ijọba aiye-kişe ti ilu Gẹsi nikan. Awọn ara ilu Gẹsi ko ni gbagbe işẹ ribiribi ti o şe fun wọn nigba ogun ajakaiye keji ti o gba wọn lọwọ oko—ẹru Hitler, ti o si sin wọn de ibiti ẹru ko ni ba wọn

Awa oniwe irohin Eleti-Ọfẹ ba Ọlọla Churchill yọ, o ku agba, o ku orire. BABA—NI—BABA NJẸ ni oriki ti a le fun oşelu nla yi.

# Okunrin Were Kan Awon Hausa Ni Ile Da Sosi Agnda Ru Ero Asoromagbesi L'Eko Ni Ilu Oyinbo

EKO—Larin ọsẹ to kọja, a gbọ wipe ọrọ di boolọ o yago fun mi ninu Ṣọṣi awọn Aguda Nla ti o wa ni igboro Eko (Holy Cross Cathedral) nigbati ọdọmọkunrin kan ja wọ inu Ṣọṣi lọ lakoko ti awọn kan nṣe isin ipade adura ọsan lọwọ, ti o si bẹrẹ si ba awọn aworan ati ohun ọṣọ inu ṣọṣi na jẹ.

Gbogbo awọn ti nwọn wa jọsin nibẹ ti nwọn si ti wa lori ikunlẹ adura ni nwọn nsare jade lọna ara pẹlu ibẹru, awọn miran sare gba oju ferẹse jade nigbati ati ba ẹnu ọna jade sita di a itiyan.

Eleyi mu ki awọn ọlọpa ti nwọn nṣiṣẹ nitosi ṣọṣi na nibiti nwọn npe ni Lion Building tete ni akiyesi nkan to ṣẹlẹ nibẹ.

Nigbati awọn ọlọpa ra wọ inu Ṣọṣi lọ, nwọn bọ mu ọkunrin na ẹniti awọn ọlọpa ni o jẹ ọkan ninu awọn oṣiṣẹ ile iṣẹ Oniwaya EKO (Post & Telegraphs Lagos.)

Lẹsẹkanna ni nwọn ba mu lọ si ile awọn alaisan nla ni Eko fun ayẹwo, ṣugbọn kawi ka fọ, o ku bamubamu ni ọjọ na.



Aworan oke yi jẹ eyin o ṣe apẹrẹ daradara kan nipa ọrọ kan ti nwọn ma npa lowe wipe ohun gbogbo ki iri bi a ti ro wọn si, nitori awọn ọmọ ilẹ Nigeria ti nwọn urẹrin musẹn ninu aworan yi ngbdanwo lati wo inu kọbọdu daradara kan wo, nwọn si tun nwọ ilẹkun aramọnda kan wo ninu ile ẹrọ Redio ni ilu oyinbo, nwọn a ma lo ariwo ṣiṣi tabi titi ilẹkun na fun ikede tabi ere kan.

Orukọ wọn ni lati apa osi titi de apa osi ọtun Mallam Mustafa Jika ati Mallam T A Musa Peters, Mallam Magwon D Nyelong, Mallam Bashari Gwazo, Mallam Adbakadri Dingyadi ati Mallam Imam Idris.

Awọn wọnyi wa lara awọn enia mẹrinla kan ti nwọn jẹ aloṣẹ ijọba ibilẹ ni iha Ariwa ti nwọn wa yẹ ẹrọ gbohungbohun (B.B.C. Studio) awọn Hausa wo ninu oṣu to kọja yi (July) ki nwọnu to ba ọkọ ... rufu pada silu ... irin ajo ọsẹ mejọ ...

# Pakute Olopa Mu Awon Janduku

ILE-IFẸ — Awọn enia mẹrin kan ti awọn ọlọpa ṣapejuwe gẹg bi "janduku" Dẹmọ ni a gbọ wipe awọn mba ṣẹjọ ninu kotu adajọ kan ni Ile Ifẹ fun ẹsun jijale pẹlu ipanilara.

Irohin na ti a gbọ ni awọn mẹrẹrin wọnyi lọ ba sinu igbo de Alufa ṣọṣi kan ti oruko rẹ njẹ Josiah Akinyẹmi ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ Olọpẹ ninu Ile Igbimọ ijọba Apapọṣe, ati ọga agba ni ile-ile iwe giga kan ni Ilesa (Ilesha Grammar School) ti nwọn si pa lara pẹlu awọn ohun ọṣẹ ni ilu Ikire ni ọjọ kẹjo oṣu keje odun yi.

Awọn ọdaran na ti orukọ wọn njẹ Raimi Akanji Sunmọla Atanda, Yinusa Abiọla ati Mudaṣiru Akanni tun gbe Alufa na ni poun mẹta ati ṣile mẹwa pẹlu moto ajapa oju ọna kan Volkswagen (Saloon) ti nomba rẹ jẹ WL 1008 ti iye owo rẹ jẹ ọtalerinwo poun o din mejo ati ṣile mẹwa (£453 10/-) ti nṣe ti Alufa na.

Nigbati nwọn ko wọn de iwaju adajọ, gbogbo wọn sẹ kanlẹ pe awọn ko jẹbi ẹsun na rara, ṣugbọn adajọ fọwọsi pe ki nwọn wa ẹniti yio duro fun ẹnikọkan wọn ni igba poun (£200) ati on gbowọ kan ni iye owo kanna.

Lẹhin eyi, ki o to di pe kotu sun gbigbọ ẹjọ wọn si ọjọ oogun oṣu kẹjọ ọdun yi eyiti wọn yio ṣe ninu kotu adajọ kan ni ilu Ogbomọsho, adajọ ti o ṣi ngbọ ẹjọ wọn ni Ile-Ifẹ kọ lati gba ibere kan ti agbẹjọro kan ti awọn ọdaran na gbe pe ki adajọ ṣe iwadi nipa aroye tabi ẹsun kan ti wọn ṣe nipa awọn ọlọpa to mba wọn ṣejọ.

Lori nkan ti agbẹjọro na nfẹ ki adajọ ṣe iwadi na ni pe awọn ọlọpa fi iya jẹ awọn ọdaran na nigbati nwọn wa ni itimọle.

Adajọ na Ọgbẹni Adeyẹmi wa dahun pe on ko le ko irin meji si inu ina lẹkanṣoso; ki on ṣe adajọ ki on si tun ṣe oluwadi ọrọ. Nwọn si mba ẹjọ na lọ.

# Eleti-Ofe Daraba

# Ijoba Da Owo Osu Oba Akarigbo Duro

IBADAN — Irohin kan de si ile işe wa laipę yi wipe awon alaşe I ti ile-işe ti nşe awoso eto nipa ijoba ibilę ni ipinlę Iwo Orun ti paşę didaduro owo oşu Akarigbo ti ilu Ijebu Rẹmọ duro, Ọba Moses Awojesi, eyiti iye rę e ẹgberin ponun mejiolelogoje (£1,142) ponun lọdun titi di igbati esi ipari ija ati etunşe ti awọn igbi. mọ kan nşe lọwọ ba jade, eyiti Ijọba Ipinlę Iwọ Orun ti gbe d de lati se eto ede-aiyede ti o wa larin Ọba na ati awọn enia rę.

Ponun marundinlogorun ni owo ti nwọn nsan fun Ọba na loşoşu.

Ijọba si tun ti paşę ba-kanna pe ki owo fun itoju ile ati ọfisi Ọba Awojesi ni ki nwọn da duro titi ipinnu yio fi ti ọdọ awọn alaşe ile-işe nipa eto ijọba ibilę jade wa.

Ikede nipa dida duro owo oşu Ọba yi ni o jẹ ọro ti Ijọba Iwọ Orun kọ sinu iwe kan lati Ibadan wa ti nwọn si ka ninu ipade igbimọ pajawiri awọn afunnişọ kan ti nşe ti kansulu ipinlę ni Ijębu Rẹmọ se ni Şagamu ninu ọşę to koja.

Nwọn ni ni ọjọ kejidinlogun oşu kęfa ọdun yi, igbimọ awọn afunnişọ to jẹ ti kansulu ipinlę Ijębu Rẹmọ fohun şọkan, nwọn si pinnu lati din owo oşu Ọba na ku si kọbọ kan pere lori ẹsun hihu iwa are ere e tabi iwa odi si awọn enia rę.

Igbimọ na tun pinnu lati da owo ọya ati awọn ohun anfani miran duro, ati lati yọ kuro lori aga ninu ile ipade igbimọ awọn Oloye ni ipinlę Iwọ Orun titi di igbati o ba ti ifę han si ala fia awọn enia rę.

Awọn Kansulu na fi ye ni pe nwọn ti sọ Afin Ọba Akarigbo di ile ipade fun ẹgbę Alakuko ati Ọlọpę lati ma gbimọ iwa ti ko nilari.




# Ijoba Ipinle Iwo Orun Pe Akeko Kan L'Ejo

IJEBU-ODE—Larin oşu yi ni a gbọ pe kotu ganran ni Ijębu Ode paşę pe ki ọkunrin kan ti oruko rę nję Rasaki Arẹgbẹ ẹniti Ijọba Ipinlę Iwọ Orun ran lọ si ilu Oyinbo ni Viena, Austria fun ẹkọ giga ati awọn mẹta miran san ojile-lẹgbẹfa pọun o le meji şile kan ati kọbọ mẹwa (£1,242 1 10d) fun Ijọba Ipinlę Iwọ Orun eyiti o ẹ gbese ti nwọn jẹ ori viyę adehun.

Oruko awọn mẹta na ni Alhaji Dadiri Arẹgbẹ ti nşe baba Rasaki ọgbẹni Emmanuel Adeneye ati Alhaji Tijani Amuludun ti nwọn jẹ oniduro fun Rasaki.

Aşẹ ti kotu ganranpa si ni o jẹ mọ ẹjọ kan ti ala şẹ eto nipa ofi ijọba ipinlę Iwọ Orun pe ọgbẹni Arẹgbẹ ati awọn mẹta fẹ gba ẹgbaa le ẹdẹgberun o le pọun mẹtala şile mẹwa ati sisi (£2,913.10.6d) lọwọn gbogbo wọn fun biba adehun jẹ.

Ninu iwe ẹjọ na alaşe nipa eto ofin ijọba ni ninu ọdun 1957 ọgbẹni Arẹgbẹ ẹniti o şi nkẹkọ nipa işẹ onşẹgun oyinbo ninu ile ẹkọ giga ni ilu Viena (University of Viena) şe adehun kan pẹlu Ijọba Ipinlę Iwọ Orun—"adehun ti ko tẹle"

Gẹgẹbi nkan ti alaşẹ eto ofin ijọba sọ o ni Ijọba Ipinlę Iwọ Orun fun ni anfani kiko ẹkọ lati ri imọ ninu işẹ işẹgun oyinbo ni ilu Londoni ninu ọdun 1957 adajọ otu na ngbọ ẹjọ yi iwe pada kan lori eyiti awọn ọlọpa fi Ọgbẹni Joseph Shaugai suu ti o si lọ şe ẹwọn oşu mẹfa fuu işẹ aşekara.

Nigbati gbigbọ ẹjọ ọdaran na bẹrẹ, o gba pe lotitọ ni on mọmọ fi eru iwe ada mọde fun apọnle lati ri işẹ na, eyiti o dabiẹnipe o f'ọwọ oloye Faui Kayọde 1957 sugbọn o kuna lati sişẹ fun Ijọba Ipinlę Iwọ Orun lẹhin aseyanri ẹkọ rẹ

"Baba re ati awọn onigbọwọ meji to ku ti nwọn f'ọwọ si iwe adehun na pẹlu rẹ papa kuna lati tẹle eto ati ilana adehun ti nwọn ti f'ọwọ si nitori ọgbẹni Rasaki" gẹgẹ bi alaşẹ eto ofin ijọba na ti sọ

Ninu idajọ rẹ, adajọ agba to gbọ ẹjọ na ọgbẹni Charles Madar kan n'i on ri'pe ọgbẹni Arẹgbẹ jẹbi ijọba fun kikuna lati fara han fun işẹ lẹhin aseyanri ẹkọ rẹ.

O ni on ri pe ijọba ti na ojile lẹgbẹfa pọun o le meji şile kan ati kọbọ mẹwa lori Arẹgbẹ-eleyi si jẹ owo sisan ati awọn inawo pẹpẹpẹ miran lori ẹkọ rẹ.

Lẹhinna ni Adajọ agba tun ni ki o lọ san pọun mejilelaadọta şile mẹwa (50 Guineas) gẹgẹbi owo irinşẹ fun Ijọba Ipinlę Iwọ Orun şugbọn a gbọ pe loya ti o gba ẹjọ fuu Arẹgbẹ ati awọn mẹta to ku ti şe asọtẹlẹ pipe ẹjọ kotẹmilọrun lori idajọ ẹjọ na.

# Eleti-Ofe Daraba

# House Of Commons Honours Sir Winston Churchill

**LONDON — Tribute followed tribute in the House of Commons yesterday afternoon when members of all parties honoured Sir Winston Churchill, who is giving up his seat after 64 years.**

**In Parliamentary language, the House "agreed to" an all party motion moved by the Prime Minister, Sir Alec Douglas Home, expressing "the admiration and gratitude of the House to the great World War II leader and Parliamentarian for his service to the nation**

After the spoken tributes a committee of leading M P s drove to Sir Winston's London home to present him with the Motion, printed on vellum and contained in a silk-lined leather folder.

Sir Alec said : "I move this resolution in the full conf dence that it will be supported by every M.P. of t is House, and in the knowledge th t all who have ever served here with Sir Winston will feel that they share at once in the sadness and in the grandeur of this essentially Parliamentary occasion.

To a silient House, heavy with emotion, Sir Alec went on : "Sadness because Sir Winston's membership of this Hous: is coming to nd e d, and grandeur bec use of the honour and lustre which the P rlame tary c ice of Sir Winston h s brought to the House of Comm ns.

"Not least of the honours of which we are sensible, was that it so evidently remained a pleasure to Church ll, until recent days, to attend our s ttings.

"Members may imagine how d ff cult it w s to decide adequately to record our thanks for this lifetime of service, but those of all parties who met to consult together were soon agreed that whatever was to be done must be something in keeping with the history of the House, in keep ng its character as the representative forum of the nation and as the House of Commons.

'We have chosen by Commons consent a method of trying to convey our thanks adopted by the House on July, 1814, in respect of the Duke of Wellington. I feel that this paecedent will g i v e Sir Winston pleasure, appealing to his vivid sense of the sweep of history.

"Today is not the occasion to review the services which he has given to the House and to the nation. For anyone that would be a daunting task."

Sir Alec said that, apart from a short interval, Sir Winston, first elected to the House in 1900, had been a Member throughout the progress of this country.

Sir Alec recaljeded hearing Sir Winston s p e a from his place below the gangway in the 1930's see ing to catch the ear of Parliament and the counry, and to give urgency to the preparation for the war which he himself had lon foreseen was deu to come."

"Then we knew him as Prime Minister in war exercising the unparalleled authority with which he commanded the House through all adversities and through taiumphs of the battle untill vic-ory was ours and his."

Sir Alec said: "Sir Wiston was a man of the strongest principles and hhld very strong ideas, but was essentially broad-minded.

"It may be tha he found the ultimate wisdom which often eludes lessr men.

"Today suffices to unite in saluting one of the most famous personalities this House has ever known and one of its most faithful servants.

## Opposition Tribute

The Leader of the Opposition, Mr. Harold Wilson, said that the terms of the motion would be welcomed by all members. This motion today is unique as the man whom we are honouring his unique. We commemorate on the eve it of his reti ement his services in peace and w r.

## Mischievous Humour

Mr. Harold Macmillan, the former Conservative Prime Minister, recca l there had been grat administrators in times of peace like Walpole, and great leaders of toe nation in times of peril and of glory like Chatham, Pi-t and Lloyd Geoge.

Otherf hos nearly equalled but not surpassed Sir Winton's immense span of Barliamentary and public Lfe-Palmerston, Disraeli and Gladstone

"There have been no doubt deb tors and orato s of equal resource and power, but few that gift of puc ise and rather mischievous humour which so endears him to us.

# 'Focus On Africa'




George Nyandoro (right), who represents Southern Rodesian People's Caretaker Concil in London, is intervied by Edward Musaka for the BBC African Service series 'Focus on Africa'.

Mr. Nyadoro had just returned from a three-w visit to Northern Rodesia, and in London he has b busy lubbying Delegates to the Commonwealth P Ministers Conference.

# Obinrin Kan J'awon Alanu Lole Ninu Moto Ayokele

IBADAN — A gbọ iroh¡n kan larin ọsẹ to kọja lati Ibadan pe dok¡ta obinrin kan, Margret Janes t¡ o nsiṣẹ ni University Teaching Hospital n¡ ilu Ibadan sọ ninu kotu adajọ kekere kan gẹgẹb¡ obinrin abiyamọ kan, Bisọla Ọdunsi ẹn¡t¡ on fi mọto ayọkẹlẹ on gbe t¡ ṣe gbe on n¡ pọnun mẹtaleladọta (£53) ninu ọjọ kejidinlọgbọn oṣu kej¡la ọdun to kọja.

Dok¡ta obinrin na lo ṣe alaye y¡ fun kotu gẹgẹbi ẹlẹr¡ ijọba ninu ẹsun jiji owo kan t¡ apapọ rẹ jẹ pọun ¡mẹrindinladorin ati ṣile mẹwa lati ọwọ awọn enia m ta kan eyiti awọn ọlọpa mba Bisọla ṣẹjọ le lori.

Dọkita Janes tun ṣe alaye pe Bisọla bere iranọwọ fifi mọto gbe on de Bedija nigbati on nwa mọto bọ lati gbangba ile Bank kan ni Agod, ṣugbọn lẹhin ti on ti ja Bisọla silẹ tan ni Ọpopo Oshrintokun n¡ Bedija, on ba fẹ apo owo on ku, ninu eyiti pọun ¡mẹtaleladọta wa. O tun sọ pe lẹhinna n¡ on ba lọ f¡ ọrọ na si eti igbọ awọn ọlọpa, ati pe ninu itọwo af¡nihan kan ti awọn ṣe on da Bisọla mọ, bẹni on s¡ tọka si.

Bakanna tun n¡ obinrin oyinbo kan to njẹ M. Waite ọjọgbọn ninu ¡ṣẹ oniṣegun (Laboratory Techuologist) wipe Bisọla j¡ on ni pọun mẹjọ ninu apo owo on nigbakan ni ọdun yi nigbati on fi mọto on gbe.

Awọn ọlọpa to o mba Bisọla ṣejẹ tun ni o ji obinrin kan, Iyaafin Francis Dawodu ni pọun marun ati ṣ¡lẹ mẹwa lakoko kan.

Nwọn ṣi mba ẹjọ na lọ lọwọlọwọ.

nwọn wa wo Onirohin wa ni ọna Pọta (Port-Harcout) ni iyawo Awolọwọ yio gba lọla ọjọ ọsẹ pada si Ibadan.

## Iyawo Awolowo Lo Wo O. o Re Ni Kalaba

A gbọ wipe gbara ti gbogbo wọn ti gunlẹ ni Kalaba, ọgba ẹwọn ni nwọn dorikọ lati lọ wo Awolọwọ ti

## Lehin Iku Oba Adele

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

Ọmọba Adeyinka Oyekan ni a gbọ wipe awọn ẹbi Oyekan fi orukọ rẹ sọwọ si ọdọ awọ afọbajẹ ni Iga. Ọmọba Adeyinka yiti wa lẹnu a ndu Ọba yi to ọjọ mẹta kan, lati ọdun kẹdogun ni on pẹlu Ologbe Ọba Adele Keji ti o waja ti kẹsẹ si ṣokoto ti nwọn nfa Oye na mọ ¡ara wọn lọwọ titi ki o to sinmi ni iwọn nkan bi ọdun kẹrin sẹhin.

A gbọ wipe awọn ọmọ ẹgbẹ Isalẹ-Eko kan ni awọn wa lẹhin Ọmọba Adeyinka Oyekan, on ni awọn fẹ ki nwọn fi jẹ Ọba tuntun na.

Ọgbẹn¡ 'Kunle Akinsemoyin ti o nṣe ¡ṣẹ nile awọn akede irohin fun Ijọba Apapọṣe n¡ Eko ni awọn idile Ọba Akinsemoyin ni awọn fẹ ki awọn fẹ k¡ awọn afọbajẹ mu. Awọn opitan ni o ti pẹ pupọ ti iran Ọba Akinsemọyin ti jọba gbẹhin.

A gbọ wipe Ọmọba Adelu Ibikunle Ak¡ntoye ti o wa n¡ Okun Alaṣia ni on n¡ oye kan ni idile Ọba Ak¡ntoye.

Ọna lati fi yan Ọba Eko t¡ yatọ si ọna ti nwọn gba ni aiye atijọ n¡toripe Ijọba ti fi ofin tuntun kan gba Ọba Eko nidi lati inu ọdun 1959. Bi awọn Ijoye bayan enia ti Arẹ ilu Nigeria ko ba fọwọ si i a jẹ wipe ỌBA LOLO ni O uwarẹ jẹ.

THE ANSWER TO TROPICAL CONDITIONS

★

UNMATCHED AFTER SALES SERVICE

★

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Lagos Phone 23310; Editor, (Olotu) Ọla Ọnatade 15, Kosọkọ Street, Lagos, P O 467, Lagos